EGBE AFENIFERE (A.G.) NI O SI NGB'ORI L'EKO

# IROHIN YORUBA

Ędn Oro Wa— "IWAJU L'ỌPA ẸBITI NRE SI"

**Akiyesi**

A lę ki awọn onibara wa ma san owo si apo wa dede, ẹnit i ko ba san owo tirę, ki o ma ya a lęnu bi a ba da a duro lojiji, a o si gba owo wa lọwọ rę

OLOTU
IROHIN YORUBA

AWỌN G.K.S. LỌ YỌ FUN EGBE AFENIFERE :AWỌN AF'ERU DIBO D'ERO EWỌN

VOL. IV NO. 691 IBADAN, MONDAY, NOVEMBER 12 1951, OWO IWE IROHIN YORUBA — KỌBỌ KAN (1d)

## Action Group Ni O Gb'ori L'Eko

Ninu gbogbo ipade ti gbogbo awọn Ẹgbę oselu nṣe ni Eko fun alaye lori eto ti nwọn o şe fun idẹra awọn enia Niyeria, eto awọn Ẹgbę Afẹnifẹre (Action Group) ni o dara ju gbogbo ti awọn yoku lọ.

Lati igbati awọn Ẹgbę Afẹnifẹre (Action Group) ti bęrę ipade wọn fun alaye kakiri igboro Eko ni gbogbo ara Eko si ti nwọ tirę lọ si ibikibi ti nwon ba pe ipade si.

Bi awọn ẹnikọkan ninu awọn Aşoju marun ti awọn Ẹgbę yi yan sode lati dibo fun ba ti bęrę si sọrọ ni oporo atęwọ o ti bęrę si dun lati ma a ti yombo wọn.

Ọgbẹni Lọya Ọbafẹmi Awolọwọ si tęe Olori awọn Ẹgbę yi paapa wa ninu awọn ti o nbi wọn şe ipade-alaye yi lojojumọ kakiri igboro Eko, bęni awọn enia patakipataki miran ti o wa lati ilu Oke mba wọn şe ipade na pęlu.

Nipa apęrę ti a nri ati eyiti a ngbo gęgę bi awọn enia ti şe nyọ mọ awọn ẹgbę yi ti nwọn si tun nję ọrọ wọn lęnu pe Ọlọrun ti o fęran wa ni O şe gbe iru ẹgbę bayi dide ni akoko yi ufi wa lọkan balę pe gbogbo enia mararun ti awọn Ẹgbę Afẹnifẹre yi yan sode ni awọn ara Eko a şe atilẹhin fun lati dibo fun wọle.

Ẹgbọn ni bę...! Afi ẹniti yio pegan Ajanaku ni o wipe on ri ẹranko kan ni igbę firi, ka ma tun ara wa jẹ ko tun si ẹranko kan ninu igbo mọ ti o to erin. Bęni awọn enia mararun yi Dokita Akinọla Majẹ, Alhaji Jibril Martin, Lọya Rotimi Williams Ọgbẹni M. A. Ogun ati N. A. B. Kotoye ti awọn Ẹgbę yi yan sode lati dibo fun jẹ ni arin igboro Eko ati ni arin ilu Nigeria gbogbo.

Bi awọn ara Eko ba duro lori otitọ gęgę bi ileri ti ọpọlọpọ awọn ti o ni ẹtọ a ti dibo nsọ, o ni lati jẹ pe ni aişe ani-ani gbogbo awọn Aşoju Ẹgbę Afẹnifẹre (Action Group) ni yio wọle. Ara Eko ẹ duro lori otitọ ati ileri nyin ki otitọ na le sọ wa di ominira.

### JAMES ỌLAKULẸHIN ŞE IKOMỌ JADE

TAMALE, N.T. GOLD COAST— Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu kẹsan ọdun yi ni ikomọ ọmọ obinrin ti Ọgbẹni James Ọlakulẹhin ti Iya-Afin rę R Adegbenjo Ọlakulẹhin bi fun un. Inawo ati ayọ ọjọ na pabambari. Jijẹ ati ọtikunlẹ foyan, Nwọn sọ ọmọ na ni Susanah Arinọla Ọlakulẹhin. Oluwa ki o da ọmọ na si, ki o si fi ire kari o.



ỌGBẸNI LỌYA ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ
Olori Ẹgbe Afẹnifẹre (A G)

### ẸRẸBẸ NI IKOMỌ J. K. ATANDA

OGBOMỌSHỌ—Ni ọjọ kẹdọgbọn oṣu keje ọdun yi ni Ọgbẹni J. K. Atanda Aşoju Olotu Irohin Yoruba ni Ogbomọşhọ şe Ikomọ ọmọ rę ti iyawo rę bi fun un ni ọjọ kejidinlọgbọn oşu kini ọdun yi ni asiko ti awọn Ijọ Onitębomi Okelerin fi ran Ogbẹni wa yi lọ si Oke-Okun lati lọ ko owo jọ fun ti ile Ọlọrun titun ti awọn Ijọ na npete lati kọ.

Bi Ogbẹni Atanda ti ti Oke-Okun de ni ija e Şọọşi wa papọ mọ ti Ikomọ-jade, ninu Şọọşi nla ti awọn Ijọ Onitębomi Okelerin ni a gbe şe isin na. Alfa J. A. Adediran ni o şe isin na, awọn enia ti o wa pọ pupọ ati awọn Ẹgbę Ọdọ Ajibinrere ti Baba ọmọ na jẹ Alaga wọn ati awọn Ẹgbę Agba Ajibinrere ti Baba ọmọ na nşe Akọwe ẹgbę wọn ati awọn Ẹgbę Tẹpamọşę.

Lẹhin isin awọn Ijọ ati awọn Ẹgbę wọnyi ba Ọgbẹni J. K. Atanda de ile. O si ti pese jijẹ ati mimu silẹ de wọn. Ẹniti o şe Alaga ase Ikomọjade na ni Ọgbẹni S. O. Lawuyi ni awọn Ẹgbę ti o si tun pęlu wa si ibi ase na ni Ẹgbę Alapata Ẹgbę Binukonu Ẹgbę Iyawo, Ẹgbę Irawọ ati Ẹgbę Alamojuto Ijọ Şọọşi Okelerin.

Ọpọlọpọ ni awọn ti o ti ilu Ajawa, Ejigbo, Agbeni ati Ikirun wa fun aşeyẹ Ikomọjade na. Bi enia ti pọ to yi bẹni Baba ọmọ na fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo wọn lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati da orukọ ninu awọn ọrẹ ati alabaşẹyẹ ọjọ na ni Ọgbẹni Sanni Ajao Alapata, John Ladiran Onifọto, Ade Fabunmi, Ade Ogundipẹ, Eman Ladiran, Eman Mogbagbeọla, Mose Adeyanju, Dan Otitọ, Daira Ọdẹsọla, James Ọmọlẹsọ. Moses Amao Taku, Eman Fayọkẹ ati ọpọlọpọ ti ko si aye fun lati da orukọ wọn. Ki Oluwa da ọmọ na si ki o si fi ire kari gbogbo awọn alabaşẹyẹ na. Amin.

## GKS Lo Yo Fun Ẹgbe Afẹnifere

Egbe "God's Kingdom Society" eyi ti Ọgbẹni G M Urobo jẹ Alaga wọn, lọ, lojọ Aiku ti işe ọjọ kẹrin oşu yi si ile Dọkita Maja ni Garber Square lati yọ fun Ẹgbę Afẹnifẹre fun işẹgun nlanla ti nwọn ni fun idibo Apejọ Nla ti işẹlu (Western House of Assembly ).

Awọn gbongbo ninu Ẹgbę Afẹnifẹre na bi Dọkita Maja, Dọkita Doherty, Oloye Bode Thomas, Ọgbẹni S. L. Akintola, M A Ogun ati F. R A. Williams si gba wọn tayọtayọ.

Awọn Ẹgbę K. G. S. na si ba awọn aşoju Ẹgbę Afẹnifẹre na ji roro lori ọpọlọpọ ọrọ fun ire ilọsiwaju ilę wa ki nwọn to tuka.

Awọn pataki ninu Ẹgbę "God's Kingdom Society" ti wọn wa fun ayọ na lojọ na ni Ọgbẹni G M Urobo G O Nkpoku N B Egwuwowu, J S Ogini, J N S Oriyemi, E A Adedokun ati P E Idiabeta

## Awon Af'eru Dibo D'ero Ewon

Ninu Idibo ti Munisipa Eko ti nwọn şe koja ni aipę yi, awọn mẹrin ni ọwọ awọn Ọlọpa tẹ ti nwọn wa fi eru di ibo. Nwọn wa fi orukọ ẹlomiran dibo pe awọn ni awọn nję bę ẹ.

Awọn meji ninu wọn Latifu Agboọla ati Gabriel Daniel gba pe awọn jẹbi niwaju Adajọ. Adajọ si ni ki ẹnikọkan wọn san pọnun mẹwa, tabi ẹwọn oşu kọkan onişẹ aşẹkara

Awọn meji yoku ni awọn ko jẹbi şugbọn ọkan ninu wọn (Mathew Chukwu) ni Adajọ sọ pe ki o san pọun mẹdogun tabi ẹwọn oşu kan onişẹ aşẹkara. Adajọ da ẹnikẹrin wọn yi silẹ nitoripe ko si ẹri ti o daju pe otitọ ni ẹnikẹrin wọn na jẹbi ẹsan ti awọn Ọlọpa fi sun.

Akiyesi:— Ki eyi ki o jẹ ikilọ pataki fun awọn ti o ba ni ero a ti ma a fi eru dibo, lati ma a jẹ orukọ ti ki işe tiwọn, ẹniti o ba tun şe iru rę ti ọwọ awọn Ọlọpa ba tẹ oluwarę iya ti awọn ijọba a fi jẹ ẹ a rekọja ti awọn ti a ruwe yi, nitorina ki ẹ şọra gidigidi.

OLOTU

# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## OTITỌ NI NWỌN NPATẸ BIBEL

Olotu, Ẹ jọwọ ẹ gba mi laye diẹ lati ja koro ọrọ ti ọrẹ mi kan sọ pe wọn ki nta Bibeli lori atẹ ọrọ yi ki i ṣe bẹẹ rara nwọn nta Bibeli lori atẹ. Ọgbẹni Joseph Alao Ayọade gbagbe pe ohun ti ko si ni ilu kan mbẹ ni ilu ikeji, ati wipe ibiti enia ba rin mọ ibẹ ni yio riran mọ.

Gẹgẹbi ibere Ọgbẹni E. A. Aiyeṣekotan ti o bere ninu iwe Irohin Yoruba ti o jade ni 17/9/51. Ko sọ asọdun rara ko si ṣasta Bibeli rara Bere-beere ki i ṣi bere rara ohun ti Ọgbẹni J. A. Ayọade yẹ ki o ṣe ni lati dahun bi o yẹ tabi lati maa patẹ Bibeli si ori igba wosiwosi nitoripe emi ni temi ri larin ilu Eko ti emi wa wipe wọn npatẹ Bibeli lori igba wosiwosi,

Mo ṣe iranti wipe ni asiko kan ti awọn Olukọ le ọmọ temi jade ni Ile-iwe nitoripe ko ni Bibeli ti Yoruba, mo waa lọ si ṣọbu itawe kakiri ako ri afi ti oyinbo ni mo nri. Ni igbẹhin ori atẹ awọn oniwosiwosi ni mo ti ri i ra.

Gẹgẹ bi ohun ti ọrẹ wa J. A. Ayọade sọ wipe lati igbati on ti nkakiri ilu on ko iti ri Bibeli lori atẹ, mo ro pe ko ti kakiri ode iru ilu Eko yi ri lo jẹ ki o sọ bẹẹ. ṣugbọn emi ko rope ẹṣẹ ni lati ta Bibeli ati Koran lori atẹ o, bi ko ṣe pe ai ko tẹle ohun ti o wa ninu rẹ iyẹn ni o le mu ẹṣẹ wa.

Olotu, aṣiri yio ma bo o.

Emi ni,
S. Ade. Lawal
(Alias Ara ko pin)
EBUTE-METTA.

## IDAHUN SI IBERE M. A. ADE

Nipa ibere ti Ọgbẹni M. A. Ade, ti Kaduna bere ninu Iwe Irohin Yoruba ti ọjọ kẹta oṣu kẹsan ọdun yi pe on ko mọ asiko ti alaye Alagba Ogbojuọdẹ jade ninu Iwe Irohin Yoruba lori "Obinrin ni aṣifẹ". Ninu Iwe Irohin Yoruba ti ọjọ keji oṣu kinni ti ọdun to kọja (2/1/50) ni alaye na wa,

Ekeji ti o tun fẹ mọ nipa ọjọ ti Wundia ba ri alejo rẹ, tabi ọjọ ti o dara lati maa ṣe inkan, alaye yẹn wa ninu Iwe Irohin Yoruba ti ọjọ kẹfa oṣu kẹta ninu ọdun to kọja (6/3/50)

A si dun mọ wa bi Olotu ba le tun wa aye lati tun awọn alaye Alagba Ogboju-Ọdẹ na tẹ jade fun anfani gbogbo awa Onkawe Irohin Yoruba.

Emi ni
Josaiah Ogundipẹ
(Ọmọ Abẹokuta)

AKIYESI:— Aye ṣi ha pupọ nisisiyi lati tun tẹ awọn alaye na jade, ti aye ba wa a o si ba nyin tẹ jade nitoripe ohun ti o ba ṣe anfani fun ẹnyin Onkawe wa ni ayọ tiwa na.

OLOTU.

E MÁA KA IWE Irohin Yoruba NIGBA-GBOGBO



ABIYAMỌ BTI RẸ MELO

Abiku ọmọ nda ọ l'amu bi?
Awọn arun wọnyi ha nyọ ọmọ rẹ lẹnu bi i

AIPERI
ỌRẸRẸ
INU-IWỌ
OSI
IGBONA
IKỌ
IGBẸ-ỌRIN
OTUTU
IBA
JẸDIJẸDI

ati orişirişi awọn arun miran ti ima yọ ọmọde l'ẹnu ni igba EHIN HIHU. Lọ ra 'YARO' awo igba arun ọmọde ni fun gbogbo awọn arun ti ima yọ ọmọde l'ẹnu.

"YARO" ko pe meji ni gbogbo ilẹ Nigeria.

Ki iwọ ki o ri i pe orukọ 'YARO' ni o wa lara Igo na ki a ma ba ta adamọdi egbogi miran fun.

O NWO EGBO SAN ṢA FI PA IBẸ



MENTHOLATUM



"Mentholatum" Fifi pa ara a ma a mu egbo ati iṣaka ara san bi idan o si rọrun lati lo. Ṣa fi pa ibẹ. Lẹsẹkẹsẹ ni "Mentholatum" ti i mu irora kuro a si mu egbo san, gbogbo awọ ara a ma a wa dan. "Mentholatum" dara fun gbogbo arun iṣaka. Ni wiwo san ati itura, itura rẹ atun maa mu ara dan, ara didan rẹ a si maa mu itura wa. Itura rẹ a ma mu ilera wa. Tete lọ ra idẹ tabi agolo kan loni.

Bere fun "Mentholatum" ganan. Eyiti o jẹ pe awọn "Mentholatum" Co. (Ltd. Est. 1889) Slough, England nikan ni awọn nṣe e.

J. A. Ajao & Brothers

GENERAL MERCHANTS
10, Egerton Road, Lagos, Nigeria

A nta awọn nkan wọnyi— Iṣana orişirişi (Matches), Oogun Iyagbẹ, (Epsom Salt), Kafura Pẹlẹbẹ (Camphor), Atike (Face Powder), Omi Didun (Mineral Water), Cement, Bata Funfun (White Canvas Shoes Leather Shoes (orişirişi), Beer, Shnapps. Gin, Wine, Brandy.

Medicine Stores

A tun nta awọn orişirişi ògun ni oke Ṣọbu wa — Oogun Narun Iba, Atun-ẹjẹ-ṣe, Ikọ, Jẹdi-jẹdi, ati ògun fun Obinrin ati Ọkunrin Lakuregbe, Ehin Ọmọde.

E ma a polowo Ọja nyin sinu iwe "IROHIN YORUBA"

Ẹ o si ri iyatọ larin bi ẹ ti ti ni onibara si ati bi ẹ o ti tun bẹrẹ si ti ni si lati isisiyi lọ.

